GUDASI KAN SESE DE LATI ILE DAHOMEY




ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. IX No. 538. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 21, 1957 KỌBỌ MEJI (2

# Oloye Are Eko Sile Nilu Ibadan



Gbajumọ alişẹfinni Oloye Tẹslimi S. Fuja, Arẹ ilu Eko ni o nlọ silu Ibadan lọ şi ile rẹpẹtẹ kan ti o kọ silu Ibadan ni adugbo baba Iyawo rẹ, (Buręda Idikan, ni'gba aiye rẹ). Ologbe Oloye Adebisi ni Idikan nilu Ibadan.

Gbogbo awọn Oloye Eko ni Arẹ pe sibi işile na awọn gbajumọ enia pataki-pataki nilu Eko ati Abẹokuta Ijẹbu-Ode. Gbogbo awọn ẹbi, ọrẹ ati Ojulumọ ni yio ba Arẹ Eko lọ şe ẹyẹ işile na nilu Ibadan, awayẹ-waye ile sisi na yio bere l'ọjọ Satide oni ati ọjọ ọla ọla ti ilu Ibadan yio fi ma dun yungba fun onile ati alejo lọdọ Oloye Arẹ tiwa "Onile k'aya k'ayọ" ni Idikan nilu Ibadan.

# Gudasi Kan Sese Dide

ABOMI-KALAFI. Kini oju ko ni ri tan nile aiye? A ti gbọ irohin kakiri agbaiye nigbapupọ nipa orişirişi awọn enia ti nwọn npe ara wọn ni Jesu, ẹ̀kẹ́bi Jesu Agege, Jesu Kalaba, Jesu Pọta, Jesu Ijẹbu-Ode, Jesu Ebutemetta ati Jesu Mẹşina, Jesu ilẹ Indi ati Jesu ilu Khartoum.

Nişişiyi ọkunrin kan ara ilẹ Dahọmi ti o wọ aşọ funfun ni awọkanlẹ ti o si di amure pupa lo pe orukọ ara rẹ ni Gudasi, (Judas Iscariot).

Ọkunrin na sọ wipe on riran, nwọn sọ fun on pe ki on jade lọ si gbogbo aiye lati ba pana orişi-rişi awọn Jesu ti o ndide, ati pe gbolohun mẹta ni nwọn fi si on lẹnu lati bere lọwọ Jesu na. Bi o ba le dahun wọn, nigbana ki a gba gbọ pe Jesu ni.

Şugbọn on ti nfi eti leko lati gbọ iro awọn Jesu na, şugbọn gbogbo wọn ti fi ara şoko nitoripe, nwọn mọ pe on Gudasi ti de.

Bi ọkunrin na ba nkoja lọ pẹlu awọn ọmọ ẹhin rẹ, ti gbogbo wọn wọ aşọ funfun bi Aladura ti nwọn si di Amure pupa yio gbe ọpa agbelebu kan dani, nwọn o si ma lu agogo niwaju rẹ, awọn ọmọde wẹwẹ yio ma korin bayi tẹle lẹhin wipe :-

Gudasi, he-ya !
O pa Jesu jẹ, he ya,
Gudasi, he ya !

Nigbati o ba de ibiti yio şe wasu yio ma wipe, ẹyin Jesu laba, ẹyin Jesu awo, emi Gudasi de lati tun wa kan nyin mọ agbelebu ẹ jade wa ahin bi o ba jẹ pe lotitọ ọmọ Ọlọrun ni ẹnyin.

# Ojola Wo'lu lo gbewure mi

ILỌRIN - Agbayanu irohin ti a ri gbọ lati ilu Ilọrin ni wipe ni ọjọ kẹrinla oşu yi ni Ejo nla ti awọn npe ni Ere wọ ilu ni Oke Pakata ninu ile Oru ni dede agogo meje alẹ. Obinrin kan ti a npe ni Iya Anifi to wa ninu ile na lo lọ wo ibiti o aso ẹran ewurẹ rẹ si, nigbati o de ibẹ, ko ri ẹran, şugbọn o ri ẹsẹ ẹwu to wa lori ẹran na ni o nwo nilẹ lẹnu Ere.

Wo poku loju ewe Kejọ

# Olopa merinlelogun lo kose ni-lu Oyinbo

Awon olopa mejila lati ile Nigeria ati awon mejila ti Ajagun (Ghana) ni o lo si ilu Oyinbo lati ko ilosiwaju ninu ise o l o p a yiyi.

Ise ti awon olopa na yio ko ni, bi a ti se nlo awon oriṣi amunimuye ati iru ona ti awa le gba fi wadi awon oderan.

Oga Olopa ti yio k o won ni ise na ni Ogbeni George Metcalf Chief Superintendent, ti o nse eleri awon ti a awadi awon ti o be daran.

Lati odun 1925 ti awon ti da ile eko fun awon olopa ilu yi sile, ogoolo-gọ awon olopa lo n wa nibe lati oririsi ilu, awon ara ile Nigeria ti o nlo fun ilosiwaju eko na n wonyi Oga Olopa A. Nagmani, C. Eashoro, Ilesha, Sergt. Aborowa, Ilo, Mayer Bawa, Corpl Nickwo, Bawali, Uwah ati Usaro.

# Iwe apunle fun ogbeni Adesina

Ironu ko to afojuba eto iwe apunle (Certificate of Honour) ti Ijoba fun Ogbeni Yesufu Adesina ti o n gbe 16, Banoko Street fun ise rere ti o se fun odun mokandinlogoji (39 years) pelu otodo labe awon Oni-se Monamona (Electricity Corporation of Nigeria) laipe yi yi.

Ogbeni Yesufu Adesina je okan ninu awon ara ilu Ijesa ti o ti de ile Eko lojo pipe, o tile le so wipe ilu Eko lagbe di gende omokunrin, nitoripe awon ero ti tagba na bi si le yi o ahoro ati eyiti o ti wa le eko lokunrin-lobinrin.

Kopero ni iyesi ojo na ti Gomina agba fi iwe apunle na le Ogbeni Yesufu Adesina lowo loju awon eti, ore ati ojulumo ninu agbala igbadun ile Gomina lojo Alamisi (Thursday) ti ise ojo kejila osu September yi.

Awa Eleti-Ofe ba Ogbeni Yesu Adesina yo, a si ba omo re Ogbeni Abdul Wahi Adesina ti ise asiwaju awon osise Eleti-Ofe yo pelu.

Otito ni Owe Yoruba to so wipe "Iwa rere l'eso enia"

# Oba Solomonu Ni Ijebu

Olotu,

E jowo, ni ilu Onitsha ni Ila-orun ti mo ti lo ni mo ti ka ninu iwe Eti-Ofe wipe opolopo Jesu lo ti de si ilu Naijiria. Beni, bi Jesu ti wa beni opolo-po Judasi si wa. Gbogbo opolopo nkan ti won so wipe o sele ninu iwe Bibeli, mo se bi inu ile aiye na lo ti se ko npe orun.

Eyin okawe mi e je mo wipe oba ti won npe ni Solomonu ninu iwe Bibeli wa si odo wa ni Naijiria nibi ri ? Bi ko ba da e loju lo ka iwe kan ti Ogbeni Gbadebo Dosunmu se nipa Ayaba Solomonu ti a npe ni Sheba, (Bilikisu ni awon Ijebu npe) ti a o ko si ilu Ijebu, ti boji re wa ni Oke Eri lati Ijebu-Ode. Mo gbo wipe ko si eniti o ngba ile iboji re ti o wa ninu igbo, sugbon ase lo nmo toto aigbaku-gba.

Iwe Ogbeni Dosunmo na dabi orin ti awon "Kiriyo" atijo ma nko bayi nipa iku Jesu:

"Emi a de be la bere wo,
Iku ta pa Jesu o,
Emi a de be la bere wo"

Emi na a lo si Oke Eri lo wo ise iyanu ti o wa nibe wa. Hadji ti wa niyen o.

Emi ni,
Olofintoto

# Gbefe Lowo Ori Nilu Ibadan

IBADAN--- Bi ko ba si erin, ese ko si. ni ti oro owo ori nilu Ibadan, Ni ose ti o koja ni a gbe gbe ofin kan jade wipe oro owo ori ko je: bi o ba ti wa ni enu ise a le ba e yo owo re lati san fun bi e meji tabi emeta sinu apo oba.

Gbefe ni oro owo ori ni ilu Ibadan o se ajoji ni o se omo onile ni oro owo ori ko mu inira lowo. Ijoba ni gbogbo owo ori ti awon ngba na awon ara ilu ni awon yio lo fun. Agbalagba oja ni lati gba owo ori tire. Akowe ko ni so ise ofe beni iyawo asunle ko ni sun ni aijeun.

Gbogbo obinrin ti o ba ti nse ise owo ni lati san owo ori ninu odun ti a wa yi.

# Amoro Bini Oyo

Obinrin kan, ara Oyo wo ile Alaruu ni Adeoyo ni Ibadan o ri omokunrin kan ara ilu Awe ti nwon fi aso we gbogbo ara re ti o wa bere si mi tea, tea. Obinrin ara Oyo na bere wipe ha ! ore mi o ha fi ara pa si ndan ? Okunrin ara Awe na si dahun wipe fi ara pa tabi kinla ? mo sebi ekute lo ha mi lijekanna bayi ? Tabi e ko ri aiye "Amoro bi ni Oyo bayi.

# Afikun Owo Ifiwe Ranse

Lati bere osu ti o mbo (1st October 1957) gbogbo enikeni ti o ba fe fi iwe ranse si ibikibi nile Oke, yio fi ontẹ (stamp) onitoro si ehin iwe na, tabi si Nigeria.

Iwe eloke-ofurufu ti nwon ti n'a ni kobo kan abo yio di kobo meji, Post Card, 2d

Enikeni ti o ba fe fi iwe ranse si ilu kan ti o si je pe ede Gesi ni awon aso ni ilu na, yio fi ontẹ onikobo merin gba sugbon enikeni ti o ba fe fiwe ranse sila ti nwon ko nso ede Gesi yio fi ontẹ Sisi gba

Eniti o ba ra Postal Order 6d ati 1/- yio san Commission 2 1/2d lori okokan lati 1/6d si 5/- Commission 3 1/3d Sugbon lati ori 6/- si £5, eyi ko yi pada rara bakanna bi o ti wa nisisiyi na lo wa.

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose [illegible] order by Air Mail for Catalogues and Literature.*
HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

Imoran rere fun gbogbo enia

Dajudaju bi kidirin inu ba nise daradara lo nmu alafia ba ara enia. Bi kidirin inu re ko ba sise deedee tabi amodi nyo o lenu nipa aiko sise deedee kidirin re — aisan bi Ebin-didun, Lakuregbe, ara riro l'orikerike, Isoto ati awon aisan bawonnii- gba o ni imoran ki o lo egbogi yi:-

**Pilules V. E. Doumer**

Egbogi ajebidan fun aisan kidirin yi je ti awon Faranse Ojulowo koyemani ninu ile ni fun gbogbo ebi.

Sile meta (3/-) pere ni. Fi owo oko ni.

**French Medicine Stores,**
18, Breadfruit Street, Lagos. Phone 23264.

# E Ma ka Iwe Irohin Eleti - Ofe

## Obinrin meji ndu oko kan

Ogbeni kan ti awon npe ni A. B. J. ti o je akowe fun Minister, ti o si ngba £75 losu, ni awon obinrin meji Jane ati Bisi mbu ara won ja ajakuakata le lori lati fi se oko.

Bi Jane ba pade Bisi, ausetuso ni awon mejeji yio fi awon so, nigbati ija na se ndi ojojumo ologo ko awon mejeji dewaju adajo.

Eni kini rojo wipe Mr. A. B. J. ti on ti afe lati igba ti o ti nse akowe ni o fe gba mo on lowo. Ekeji rojo wipe Mr. A. B. J. yi, on ti afe o jo ti pe, on pelu re ndi nana po, iya re mo eo, baba re si mo on pelu.

Lati le ri ri okodoro oro yi siwaju, adajo ranse lo pe Mr. A. B. J. lati gbo ti enu re, A. B. J. so fun adajo wipe, awon mejeji le npese lati fi on se oko, sugbon on koiti yan eni kan pataki ninu won, ayafi nigbati o ba le fi owo si iwe adehun ti on yio se. Adajo dahun pe ki o lo ko iwe adehun na fun on wa, ni awon ba ye ojo na si ojo keji.

Nigbati ile ojo keji mo Mr. A. B. J. yo iwe adehun na fun adajo, nigbati o si pase wipe, ki awon ka iwe adehun na. Iwonyi ni oro ti o wa ninu iwe na:-

1 Lehin ti o ba fe mi tan, iwo ko gbodo tun ni oko miran a yafi emi A. B. J.
2 Iwo ko gbodo ba okunrin kan ko ago e sugbe wiwo.
3 Iwo ko gbodo fi agbara tabi tulasi mu mi se nkan ti okan mi ko fe se.
4 Iwo ko gbodo ra oja awin si mi lorun lailai fun mi tele.
5 Iwo ko gbodo gbe oju ako si eni oko re, beni iwo ko gbodo ko egbe kakiri ode.
6 Iwo ko gbodo le owo oniko wa fun ti ra ohun oso ti ara re.

(Wo ipekun leyin ewe keji)



# ELETI OFE

ANIGBORON KO SI WIWO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P.O. Box 407 Phone 23370

VOL IX NO. 375 LAGOS, SATURDAY SEPT. 21, 1957


## Ijoba Ghana Yi Ma Le o!

A gbo ti ese kan bo sodo, Oni gen, ni owe ti a le pa si oro ijoba Ghana yi, gege bi o ti je wipe Asaju (Ekonder) se mu koko gu o gu ina yi.

Ohun ti ako ti ri a rwi, niti awon eola meta ti ijoba Ghana yi li sfin wa kuro nilu, k'awi kafo, ijoba yi banun tun se ofin wipe Loya Oyinbo olole nla Q.C. t awon ti ijoba Ghana afe ba se ejo g e, ti o si ti joko ni akobere ejo na ti Kotu ri se ki ijoba lo san owo irin-ajo ko gbodo tun wo ilu Ghana mo. Eyi ara!

Nje ki o ha se wipe bayi ni awon ti nwon ti si waju gbe ijoba oninira ti nlo ijoba won na, ko ha ni di anfani fun awon eniyan ti ilu won ba gba ijo'u ominira na bi?

O ye ki ijoba Dokita Nkrumah fise-dena ki nwon, maa se pelepele ninu ohun gbogbo, ki nwon mafi ijoba won gun ngere elese kan ti igi se ko ni pe ki o to se.

Ijoba Ghana yi se kelebe!

## ANFE ASOJU

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofe lati fi kun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko si isale wonyi:-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe, 28, Kosoko St., Lagos


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu. Iko ati ohun gbogbo miran ti o ma mba omode ja ni asiko eyi. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si ri wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(Ede Meji Abo Jiko Fun Igo Kan)

O wa Lodo

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS



No. 73/S.2/Vol. VIII/505

# Ministry of Education, Western Region

## Vacancies for Teachers for Domestic Subjects

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Teachers in Government Domestic Science Centres.

Scale of Salary : D. 1, 2, 3 - £150 - 198, £207-258, £210-360;

Point of entry according to qualifications and experience.

QUALIFICATIONS - Grade III Certificate (Domestic Science) or Grade II Certificate with Domestic Science and Needlework qualifications, and teaching experience.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 39 Vol. 6 Notice No. 787 of 22/8/57.

Closing Date : 30/10/57.


## Mbadiwe di baba Ikeka—tape



EKO. Iyawo olola K. O. Mbadiwe lo bi omo okunrin kan fun oko re Ogbeni Mbadiwe, nwon si so oruko omo na ni oruko Oyinbo oruko Ibo ati Yoruba, ki o ma ba da ija sile. Omo na nje George Iheayinsuku Ayodele.

Nwon somo na loruko ni ojo 14th osu Sept 1957, ninu Sosi Aguda, Eniti a nwo ninu aworan yi ni baba Tunfulu na, olola K. O. Mbadiwe.

Ole ninu awon olola ati awon ijoba ti o wa sibi isomo loruko na ni Olola Sir James Robertson ati iyawo re, Archbishop Dr. Leo Taylor, T. J. Moran M. N. Ugochuku Kola Balogun ati opo enia ti a ko ri aye lati daruko tan.

Olorun ko da omo na si.

# Gomina agba da Orisu sile.

Gbuke ni a gbo irohin wipe Dokita Nwafor Orisu, enit awon ba se ejo jibiti ti awon si ju si ewon odun meje, ni Gomina agba, Sir James Robertson sanu fun o si da a sile kuro ninu Tubu.

Ohun ti o fa sababi ti nwon fi da a sile ni wipe, opolopo enia lo nso wipe o nronu popoju ati nipe bayi, o ru kangagan.

Enikan so wipe nigbagbogbo ni on ma nlo bewo ninu ogba ewon ati wipe laipe yi lo ko iwe kan si on, nigbati on ri ede Gesi ti o ko sinu iwe na, o ya on lenu, nitoripe omo ti o nka iwe standard 1 ko gbodo so oyinbo be, o si rope boya ori re lo fe daru, nitoripe o mowe lobe ti o ti gba oye iwe mimo ni University ilu Amerika.

A gbo wipe yio pada sile re ninu ose yi Kabiyesi Nwafor Orisu, o ku ewu.

# Emi ko mo Alatako

Ogbeni kan ti o nse asoju egbe U.N.I.P ti nwon npe ni Ubani Ukoma, lo so fun Tafawa Balewa wipe o ye ki o yan alatako ninu igbimo yi ki won to tun se ipade igbimo m i r a n. Nitoripe, egbe Afenifere ko wi fun awon ijo ti so nigbati Tafawa-Balewa fi pe won lati wo igbimo ijoba ile Nigeria.

Bi Ogbeni na ti soro yi tan n w o ni gbogbo enia kanu bo o awon si b e r e lowo re wipe ewo ni egbe tire ? Ogbeni na dahun wipe U.N.I.P ni egbe ti on. Gbogbo awon igbimo si ki gbe pe yege de l ojo ti o n.

Ogbeni Ubani - Ukoma dahun wipe lati oni yi lo egbe U N I P ko ni ba egbe Afenifere se po mo. Sugbon eto lo je fun Tafawa Balewa wipe ki o to ko ijoba re jo bayi o ni lati fi si eniko egbe ti on tele ti o ti ijoba kan ti ko ba ni Alatako yi je ijoba Alade. Gbogbo awon igbimo si dahun wipe rara Nda o Agbedo ko le ri be.

Tafawa Balewa fesi da okunrin na lohun wipe: oro ti o nibere yi fun enia ni idaraya lojo na rara wipe ogbeni Ubani-Ukoma yi ti bi on bere nipa kan Ese ti a ko yan enikan ninu egbe U.N.I.P. si igbimo ijoba ile Nigeria. Tafawa so siwaju wipe on ko le so pe Ogbeni yi nfe ki a fi on je ye Minister tabi o nfe ki a fi on joye olori alatako, ko nse iru eniyan bi Ogbeni yi ni so yen.

Emi ko gbe meji rara mo a gbo pe ijoba wa yi yio le sise rere ninu ilu wa yi nitoripe ero kanna ni awa ti o mbe ninu re ni okanna si ri ipinnu wa.

# Igbimo Ibile Yo Malam Laaro Kuro Ninu Ise Igbimo

ILORIN. Ijoba ibile Ilu Ilorin ti yo Malam Laaro kuro ni Alaga igbimo ijoba ibile, nwon yo petapata, kuro ninu egbe Afenifere, eyi nikan ko, nwon yo kuro ninu gbogbo awoyo ti o fi ara mo ti egbe Afenifere. Eyi ni ohun ti fa opolopo ayipada laarin ijoba ibile Ilorin.

Ogbeni J. G. Ekunrin, ni a fun gbe pe si ipo ti Malam Laaro ti nse itoju te ri. On ni yio ma se ofintoto gbogbo bi owo ti nlo si ninu igbimo na.

Igbimo ijoba ibile ti yan gbinan lati je oye Agbaniseye (Returning Officer) ninu ise ijoba.

A gbo wipe lati igbati egbe Afenifere ti bere iseju nilu Ilorin, ni oalpese si je awon alagidi okan, ilu toro, ohun gbogbo si nlo dede.

# Akowe Agba Sir Ralph Grey



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Sir Ralph Grey ti o ti nse Sekitari agba fun ile Nigeria tele ri, ni o ti di Adele tabi igbakeji Gomina agba ni ilu Eko nisisiyi.

Eyin okawe wa yio ranti pe nigbati nwon pada de lati ilu oyinbo ti nwon lo se ejo ile ni alagba Ralph Grey yo kuro ninu ajo igbimo awon Alakoso ise ilu wa.

Oye na yio mori o.

Bi o ba fe je Gbajumo

Ra BICYCLE

Siga Gbajumo ile Nigeria.



# Oloye Kola Balogun



Eniti a nwo ninu aworan yi ni oloye Kola Balogun, eniti o nse Alakoso (Minister) fun Ise Iwadi awon ohun ijinle ati Alarena fun Ijoba ile Nigeria. On lo nse ofin toto lo silu Amerika ati Kanada lati se iwadi ohun ti yio jeki ile Nigeria ati ile nwonyi ni ajose papo ti ao si ma gbo irohin ara wa dedee.

Nigbati o ba de ohun, yio ba awon awujo onilwe irohin soro, ati Igbimo Radio Television, ati awon ti o nse ere Cinema.

Bi Oloye Kola Balogun ba nlo yio ya silu London, yio ba Ogbeni Mbu Soro, yio si mu Ogbeni J. Stocker dani pelu.

# Awon ina pataki ti o jo silu Eko

(Apa keji)

Gegebi a ti mba ọrọ wa bọ, awọn ohun ti o ba ṣe pataki lasiko ti nkan na ṣẹlẹ si nwon fi nṣe apejuwe lati ṣe ipinu gẹgẹbi nkan na ti pẹ to. Ina jijo si jẹ ohun ti o nṣaba nwa nṣẹlẹ si ọdọdun nilu Eko igbani, nitori ewe ebiba tabi ikin ni awọn ti mbọ ori ile lasiko na. Lọsẹ ti o kọja, ibiti a se apejuwe awọn ina ti o ti njo nilu Eko de ni ina Apongbọn ti o jo titi wa de ita Balogun ninu ọdun 1878.

- Ina ita Martin keji titi lọ de ilewe Sọrẹfuṭu 1879.
- Alakoro ... 1881
- Ita Balogun 1883
- Olowogbowo titi lọ de Isalẹ Eko 1884
- Ofin, nibi eyiti ọmọde kan jona sile 1881
- Itolọ 1881.
- Kosokọ ninu agbole re 1885.
- Agọ Hausa 1886
- Idumọta 1887
- Okepopo 1887
- Ita Badina 1887
- Elẹgbata 1887
- Idumagbo 1888
- Ẹnu-Owa 1891
- Idunṣagbe 1892

# J Stocker



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni J. Stocker, ti o nse Olotu Federal Information Service, on ni a gbo wipe yio tele Oloye Kola Balogun lehin lo silu Amerika ati Kanada lati se ofin toto ona irorun, ti ile Nigeria, Amerika, ati Kanada yio fi ni ajose ti nwon o si ma gburo ara won. O dabo o, Oko arelo o.

# Obinrin meji ndu oko kan

(O bere loje ewe keta)

7 Iwọ ko gbodọ huwa igberaga si emi ọkọ rẹ ranti pe emi lo nṣe atije ati atimu rẹ.

8 Iwọ ko gbodọ ṣe oju kokoro si ọkọ ọlọkọ bẹni iwọ ko gbodọ korira awọn ebi ati ore mi.

9 Ohunkohun ti o wu ko o jẹ aṣiri laria emi pẹlu rẹ. Iwọ ko gbodọ ta sita, o si nilati jẹki iyo owo ti mo ba fun ọ, ki o tọ ọ lọrun.

10 Iwọ ko gbodọ gbe ori soke si emi ọkọ rẹ, ọrọ ti mo ba sọ fun ọ ni o nilati gbọ.

Lẹhinti nwọn ti kawe yi tan, Bisi tako lati fi ara mọ, ṣugbọn Jane fi ara mọ. Ni adajọ ba fi ara mọ wipe ki Jane ma fi ọwọ mu ọkọ, ki Bisi lọ wa ọkọ tirẹ.

**E Ma ka Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.**

# Influenza De Ilu Ilorin

ILORIN. O keri alaye ago pirlati, lati Ilorin ni irohin ti de wa wipe, arun Infuenza ti o nja lode yi, eyiti awọn npe ni Ayọkẹlẹ tabi Ge-slow ti de Ilorin.

Ati wipe, nwọn ti ngbọ re rẹ ṣiwaju ki o to de ọdọ won, ati bi ẹru ti nbẹ ni ara pẹ. Niserina, ni gbẹra ti nwọn ri ọwọ rẹ, ni Alaiyeluwa oba Ilorin, pe gbogbo awọn Lemomu-Lemomu jọ pẹlu awọn jẹnmọ wọn, awọn ke tira, awọn kirun, awọn si ṣe adura, awọn pa malu mọta.

A gbọ wipe a se iwọn ọdẹtọla ọnla to wa ni dubule aisan na ni lilọlọyi. Bakanna ni aisan yi nfi oju wọn ri ẹnikẹni silu Kabba.

Awọn Olutọju alabiyamo ati awọn aboyun ati awọn ti o nigla aisan ko le wa ṣe itọju wọn nkọdpe awọn na papa ti serike, ti awọn si nwa eniti yio ṣe itọju awọn na.

No: 134

## "Notice To All Employers

### "EMPLOYMENT AND EARNINGS ENQUIRY- SEPTEMBER, 1957

"The return of employment and earnings is called for each year in September under the provisions of Section 14 of the Labour Code Ordinance.

"The enquiry will be conducted this year on the same lines as last, and the attention of all employers is drawn to the need for their complete co-operation in this matter if the enquiry is to be a success and the information is to be of value. Employers may be assured that the information will be treated as strictly confidential.

"The forms, and full instructions as to their completion, will start to be distributed in September. If any employer of 10 or more persons has not received the form by the end of September, he should immediately get in touch with one of the Labour Offices in the following places:-

| | |
|---|---|
| Northern Region - | Kaduna; Kano; Jos; Bida. |
| Eastern Region - | Enugu; Aba; Calabar; Abakaliki; Port Harcourt. |
| Western Region - | Ibadan; Warri; Benin; Sapele; Akure; Abeokuta. |
| Lagos - | Alakoro; Marina. |
| Southern Cameroons - | Buea. |

"All employers concerned are requested to complete and return the forms to the nearest Labour Office by the 20th November, 1957".

# Dokita Azikiwe Wi Re!



EKO. Ko si omoluwabi kan ti yio ka iwe ti Olola Dokita Azikiwe ko si Oloye Obafemi Awolowo nidi oko ni Apapa ti ori re ko ni wule.

Bi Oloye Awolowo ti gunle si Apapa ni nwon fi iwe na le lowo o jas o ka a o si ri wipe iwe na jade wa lati odo Olola Dokita Azikiwe. E jeki a gbo ohun ti iwe na so gegebi nwon ti wi.

Kabo o Oloye Awolowo awa ogenna gbomgbe metera ni ise nla pupo lati se niwaju wa nitori ki a le so orile ede wa di okan soso.

Iranlowo wa ti a se fun Alhadji Tafawa Balewa lati le da ijoba kan sile Nigeria je eri wipe awa Premier mete-ta nfe ki ijoba ile Nigeria duro gbonin ki a si ni alafia.

Jowo, me fe ki o gbagbo wipe tokantokan ni mo fi nso oro yi, wipe bi o tile je pe iyato mbe ninu iselu wa si ara wa gegebi osela, eyi ko di ajumose wa lowo ki a le gba ominira fun ile wa laipe.

Iwe paapa alara mo wipe oko ni ibiun si o ni okan mi tabi si Sardauna, gbogbo wa lo si ti fi ohun sokan lati jijo gba ominira fun ile wa.

Gbagbe ohun ti o ti koja; ki o si jeki afi okan wa si ohun ti a nlepa pelu igbagbo wipe gbogbo nkan nsise fun rere.

Enyin okawe wa aje mo bere tani le gbo iru oro yi ti ori re ki yio wule,

A tile gbe pe iyalenu ni iwe na je fun Awolowo nigbati o ka iwe na tan, o si salori lati fesi re gegebi Omoluwabi.

# Awon ara-iye nki Prime Minister Nigeria

Ogbeni Lim Yewhock O.B.E Prime Minister ilu Singapore, lo nki Tafawa Balewa bayi:-

Mo ba o yo gidigidi, lori oye Prime Minister ti a gbe le o lori, ti o si je ise ni eni akoko ti o koko gbe oye na ka ori. adura mi ni wipe ki Olorun oba ma se olurànlowo fun o siwaju.

IDAHUN

Alhadji Tafawa Balewa fesi dahun pe Mo dupe pupo fun adura re ti o fi ranse si mi, mo si ni-nu didun lati ba enia bi tire kegbe ati awon ara Singopere nitoripe iranlo-wo nla ni yio je fun mi nisisiyi ati ni jomitan.

GHANA

Inu mi dun jojo lati ba o yo, ti o fi je wipe iwo ni eni akoko ti o koko joye Prime Minister tile ile Nigeria. Ki Olorun jeki igba re tu gbogbo enia lara. Emi yio si ma foju sona akoko ti ilu wa mejeji yi yio ni ifowo-sowopo.

IDAHUN

Mo dupe jojo fun waya ti o te ranse si mi, ti o fi ba mi yo, mo gbadura ife ti o ni sinu nipa ifo-wo-sowopo larin ile Gha-na ati ile Nigeria fun opo odun ti o mbo.

# Bi Erinle tise di Orisa ni Ilobi

Awon Arokin so pe ni-gbati ogun Eledowe le ni Balogun Kara tako pe afi bi on ko ilu Oshogbo, nse ni Erinle jade lati inu odo, ofa ti o si koko ta, nse lo wo oju Balogun Kara lo ni ogun Ilorin ba sepe.


## Kere o!

A ti ni original ogun German to sese de, fun onigunu aisan tokuento tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO**

**BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



No. 135

## YABA & LAGOS DOMESTIC SCIENCE CENTRES

Evening Classes open to adult women will commence on the 23rd September, 1957 at:

(1) YABA DOMESTIC SCIENCE CENTRE,
8, Mc Ewen Street, Yaba.

(2) LAGOS DOMESTIC SCIENCE CENTRE
13, Idolowo Street, Lagos.

Applications for admission by letter or interview with the Women Education Officers-in-charge.

Time Tables.

YABA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Monday & Friday | — | Dressmaking. | 5-8 p.m. |
| Tuesday | — | Millinery & Beltmaking | 6-8 p.m. |
| Wednesday | — | Cookery | |
| Thursday | — | Embroidery & Knitting | 5-7 p.m. |

LAGOS

| | | | |
|---|---|---|---|
| Monday & Friday | — | Dressmaking | 5-8 p.m. |
| Tuesday | — | Embroidery & Knitting | 5-7 p.m. |
| Wednesday | — | Cookery | 5-8 p.m. |
| Thursday | — | Millinery & Beltmaking | 6-8 p.m. |

Fees are payable in advance at the rate of £2 : 10 : 0d. for the entire course or individual subjects may be paid for separately. Students must provide their own materials.

# Alapara Ibadan nki yin o

OKO POKO
Ibadan

Emi ko mo pe Oghoni P. A. Afolabi ti emi pataki to be ni adugbo ilu Oyo a fi igba ti mo [illegible] be oko egan mi wo si ilu Shaki ti mo pada re [illegible] Oghoni Lekanle [illegible], oruko ma [illegible] oro si. Won [illegible] ati Bandele Bello.

Emi ki [illegible] ojela gagbon mo ti mo Pa Afolabi ti pe igba [illegible] mo ngbe ebela lowo Iglia Padi-Agada.

Awa lowo ma pe mi ni Olo-[illegible] Alala, Tisa Afolabi ati Tisa Antoni Laotan, baba ti won je fun mi, omo Oyo ni won-won ti ko wa bi a ti se bawo fun egba. Tisa gidi ni won.

Mo tile ma gbadun owo Afolabi lori dura ti o be ere orin fun wa ni Sesi nla ti Agada l'Eko. Wa ma gbo bayi

"E ti emi gba kana o,
Mo mo wipe be ni,
Toye omo Eko ti o,
Maria gbo adura mi"

Ti owo emi Alapara ba te ni wa me wipe mo mo orin ni ko ni ekun rere. Iyen be, Pa Afolabi, ki lo se ti e ko ti mo mi lowo ko, ni ilu ejo ti [illegible] Fyal o ko ni ona Iyesi, tabeli. Shaki ati Igboho ni mo wi o, emi na ko ko, bi o ba se ti omo dida mo da bi o je ti oro sise ma so, bi o se ereke ebu oko si je alle kia nio yo nafila ebu si awon si ko ne wipe Alafia pataki, Afolabi pataki" Iara. Mo si mo ariwo pe teran ti a be eso oro" kanpani" tabi e ti ope Iro ti e mo ope nita kakiri yen.

Mo je ijo na kara kara. Iyen wipe Iro ni emi Alapara Ibadan epa tabi oslu ti o pe ara re ni Ayanpero ara. Ikehin omo Abeni, fin eye kiki egan. Niteto ebikan ki fa gba je Alapara Ibadan nki yin o.

## Lehin Ogorun Odun Oku Ojo Martins sipo pada

EKO. Irohin ti o gbeji kan ni ti Daddy Adebayo Ojo Akangbe Martins eniti o sainisi nile aiye ni ojo 8th osu Feb 1857, ti awon si sin ku re sibiti a mo ni oju Orori Ojo Martins ni opopo Martins Street nilu Eko, ni egbe ile onje ti a npe ni Bristol Hotel ti awon Igbimo L. E. D. B. ranse pe gbogbo awon omo-omo ologbe na wipe, awon fe lo ibiti baba won Ojo Martin gbe sun si nitorina, ki awon so ohun ti awon o gba ni awon nkan etutu, ki awon si hu oku baba won na ti o ti ku lati iwon ogorun odun sehin, ki nwon lo sin si aye kan ti awon Igbimo L. E. D. B. yio fun won ni Garber Square, alta Akanni.

Bi a ti gbo itan Ojo Martins si ni wipe awon Onisunmemi lo kii mole ninu oko, gegebi o si ti je ara Ijaiye awon ta leru fun awon Potogi nwon si wa a lo si ilu Brazil.

Nigbati owo eru pin, o ba oko Da Rosa (Da Rocha) wa si Saro, Nilu Saro lo gbe wa, ti Irohin kan kakiri wipe awon ara Agbadayigi Segun awon Idahomi ni aiye ko soka. Inu awon enia ti o je omo Yoruba dun Ojo Martins wa ninu awon ti o koko ba oko Da Rosa gunle si ilu Agbadayigi, Lati ibe lo ti wa tidi ti silu Eko.

Ko iti pari


NI IRANTI

ANTI WA OWON
Ologbe
MORADEWUN AMOPE

Eniti o fi aiye yi sile lo simmi ni ojo ketadinlogun osu September 1955.

Sunre! Sunre!! Sunre!!!

Morano Ayinde Thompson
Tajudeen Thompson
Ayinke Thompson


# Ojola wo'lu lo gbeware mi

(Obere lati owo kan)

Nigbana ni obinrin na ke pe omo re pe ki o wa wo okan ti ebri, ki a ma fa oro gun, ni nwon ba ranse si Bandawaki, eleyini ni olori tabi oloye adugbo. Ni kukuru, won ranse pe olori ode ti o wa nitosi won, olori ode na lo pe Ere na. Nigbati nwon le lau re, nwon ba ogidi Pepeiye kan ati adie akuko ela kan ninu re. Ejo na gun to ose medogbon.

A gbo wipe nwon ti pa iru ejo na niwon osu medogun sehin. Oruko abata ti ejo yi ti jade wa ni won ope ni abata naihunl'ewoje.


# Orin Rekodu Aladun

DECCA RECORDS

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1936 | Anti Elerogbe - Ajao | 1947 | Baba Paulla - Kokoro |
| 1937 | Ma Fi Iya Je Mi - | 1948 | Mo Rohun F'Olu - " |
| 1938 | Adeinka Adegeke - Adio | 1949 | Oba Olowa Ye - Ligali |
| 1939 | A Nlo Ri Awoleyes - " | 1950 | Owo Ori B - " |
| 1870 | Esi Oro Nyin - Aka | 1951 | Mole Bawon Sure - " |
| 1871 | Omo Adre - " | 1956 | London Conference-Lagos Day |
| 1872 | Abenije - " | 1957 | J. K. Randle - Lagos day |
| 1940 | Awon puropure - " | 1931 | Asewo Debin - Llado |
| 1941 | Ija Wa Fori - " | 1970 | Koshoni Randle - " |
| 1942 | Mase gbagbe mi Ejire | 1971 | Rio Lindo Baba - " |
| 1943 | Oya ota; Alaiye - " | 1972 | London Conference " |
| 1944 | Irawo Olayele - Haruna | 1973 | Ibo Nyin Wole - Shewara |
| 1945 | Abasi omo Aja - " | 1975 | Omo Iale Aiye - Bale |
| 1946 | Lare Johnson - " | 1976 | Oro Eko - " |

6/- eye kan. Owo - oke lete. Bere owo arapo lodo wa.

**Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta. Ati awon Eka re.



# Lati fun o lokun-inu ati agbara re pada

Lehin
AMODI INFLUENSA
lo egbogi

**Hommel's Haematogen**

polu Wara tabi Oti Waini fun ose kan tabi meji

A le ra ni Sobu ti awon nta egbogi ati ni gbogbo ile taja

ALAKOSO EGBOGI NA NI-

**ALBAN PHARMACY LTD.**
2, VICTORIA STREET,
Lagos.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 487 Lagos Phone [illegible]